# IJỌBA ẸGBẸRUN ỌDUN ATI IDAJỌ IKẸYIN

## Ifihan 20:1-15

## ẸKỌ 465 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Awọn ẹni-iràpada OLUWA yio padà, nwọn o wá si Sioni ti awọn ti orin, ayọ̀ ainipẹkun yio si wà li ori wọn: nwọn o ri ayọ̀ ati inu didùn gbà, ikãnu on imí-ẹ̀dùn yio si fò lọ" (Isaiah 35:10).**

**I Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun**

1 A de Satani fun ẹgbẹrun (1,000) ọdun, Ifihan 20:1-3

2. A fi itẹ ati aṣẹ fun awọn eniyan mimọ́, Ifihan 20:4; Orin Dafidi 149:6-9; Daniẹli 7:22; Matteu 19:28; Luku 19:17; 1 Kọrinti 6:2; Ifihan 1:6; 2:26, 27; 3:21; 5:10

3. Awọn eniyan mimọ́ ti akoko Ipọnju ti a pa gẹgẹ bi ajẹriku ni a o ji dide lati wà laaye ati lati ba Kristi jọba, Ifihan 20:4, 5; 6:9-11

4. A sọ ti ipò ologo ti awọn ẹni ti o yẹ fun Ajinde Kin-in-ni yoo wà, Ifihan 20:6; 1 Kọrinti 15:22, 23; Filippi 3:10, 11;1 Tẹssalonika 4:16; Heberu 11:35

**II Idajọ Ikẹyin**

1. A tú Satani silẹ o si tan awọn orilẹ-ède lati lọ jagun; a ṣẹgun rẹ̀ a si sọ ọ sinu adagun ina, Ifihan 20:7-10
2. Itẹ Funfun Nla kan ati Onidajọ kan ti a kò le ṣe apejuwe rẹ̀ fara hàn, Ifihan 20:11
3. Awọn òkú iyoku ni a mú wá sinu idajọ, Ifihan 20:12, 13; Heberu 9:27; 2 Peteru 2:9; 3:7
4. Olukuluku ẹni ti a kò ri orukọ rẹ̀ ninu Iwe Iye ni a sọ sinu adagun iná, Ifihan 20:14, 15; 21:8; Isaiah 5:14; Marku 9:44; 2 Peteru 2:3

## ALAYE

### A tẹ Ori Eṣu ba

Ninu ẹkọ kan ti a ti ṣe kọja a kọ́ nipa iṣẹgun awọn ogun ti wọn dide si Oluwa Jesu ati awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀. A ri pe a di ẹranko ati wolii èké naa ni igbekun a si sọ wọ́n sinu adagun iná. Agbara ibi ti o wà lẹyin ẹranko ati wolii èké naa ni Satani funra rẹ̀. Nitori naa ẹkọ wa oni bẹrẹ pẹlu idajọ ti o kan ẹni ibi yii, gẹgẹ bi ọmọ-alade agbara oju ọrun, ti o ti n dari awọn ti a kò i ti tunbi, bẹ̀rẹ lati igba Iṣubu ninu Ọgba Edẹni.

Agbara kan wà ti o ju ti satani lọ, ni ainiye igba ni oore-ọfẹ igbala Jesu Kristi ti sọ imọ eṣu di asan nigba ti awọn ọkàn ba wá si Kalfari nipa igbagbọ́. Jesu wi pe, "Gbogbo agbara li ọrun ati li aiye li a fifun mi"; Satani kò si tun le ṣakoso ọkàn ti Ẹjẹ Jesu ti wẹ̀ mọ́.

Nipa agbara Olodumare, angẹli kan sọkalẹ lati Ọrun wá o si bori Satani patapata, o sọ ọ sinu ọ̀gbun ainisalẹ. Eyi yatọ si ibi adagun iná ninu eyi ti a sọ ẹranko ati wolii èké nì si. Lai ṣe aniani eredi eyi ni pe a o tun tú eṣu silẹ lẹyin ẹgbẹrun ọdun, a kò ri kà ni ibikibi ninu Bibeli pe lẹyin ti a ti gbé eniyan kan sọ sinu adagun iná pe ẹni naa tun jade. A kà ninu ori kẹsan-an iwe Ifihan pe a ṣi iho ọgbun ainisalẹ naa silẹ lati ṣi ayè silẹ fun awọn eeṣú ti a fun ni agbara bi ti akeekee ilẹ̀ lati jade lati maa dá araye lóro fun oṣù marun-un. Nisisiyii bìrì ti yipada, a si sé eṣu funra rẹ̀ mọ gbọningbọnin ninu ibi ti o ba ni lẹru yii fun ẹgbẹrun ọdun.

### Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun

Iyipada nlá nlà ni yoo ṣẹlẹ lori ilẹ ayé ni akoko yii. Awọn eniyan mimọ́ yoo jẹ ọba ati alufaa, labẹ Ọba awọn ọba ati Oluwa awọn oluwa. Ninu iṣẹ ti a rán si Ijọ ni Tiatira Jesu wi pe, "Ẹniti o ba si ṣẹgun, ati ẹniti o ba pa iṣẹ mi mọ́ titi de opin, emi o fun u li aṣẹ lori awọn orilẹ-ède: on o si mã fi ọpá irin ṣe akoso wọn" (Ifihan 2:26, 27). Egún ti o ti wà lori ilẹ nipa ẹ̀ṣẹ awọn obi wa akọkọ ni a o ká kuro, aṣálẹ̀ yoo tanná bi òdodó, awọn ẹranko buburu kì yoo tun pa ara wọn tabi awọn eniyan lara mọ́, irora aisàn ni a o mú kuro, ododo yoo si jọba lati opin ilẹ̀ de opin ilẹ̀.

Ajinde pin si ipa meji – a mọ̀ ọ̀kan ni Ajinde Kin-in-ni, ọ̀kan ti o kù ni a n pe ni ajinde keji tabi ajinde ikẹyin. Oluwa Jesu sọ pe ajinde iye yoo wà, ajinde idajọ yoo si wà pẹlu (Johannu 5:29).

**Ajinde Ekinni**

Ni tootọ Ajinde Ekinni yii jẹ ajinde ti yoo ṣẹlẹ ni iye igba ọtọtọ, a si fi wé ikore-wale. Kristi ni Ẹni kin-in-ni lati jade lati inu iboji pẹlu ara ologo, Paulu si n tọka si I gẹgẹ bi akọbi (1 Kọrinti 15:23).

Lai ṣe aniani apa ti o pọju ninu ikore naa ni a ṣe apẹẹrẹ rẹ̀ ninu Ifihan ori kẹrin ati karun-un nibi ti Johannu ri ti ilẹkun kan ṣi silẹ ni Ọrun ti o si ri ẹgbẹ́ nla ti n kọrin pe a ti ra awọn padà lati inu ẹ̀ya gbogbo, ati ede gbogbo, ati inu eniyan gbogbo, ati orilẹ-ede gbogbo wá. Eyi jẹ́ idahun fun alaye Paulu apọsteli nipa ajinde awọn okú ninu Kristi ati Ipalarada awọn eniyan mimọ́ alaaye, ti a sọ ninu 1 Tẹssalonika 4:16, 17.

**"Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ lati ọrun wá ti on ti ariwo, pẹlu ohùn olori awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn okú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde;**

**"Nigbana li a ó si gbà awa ti o wà lãye ti o si kù lẹhin soke pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li oju ọrun: bẽli awa o si ma wà titi lai lọdọ Oluwa."**

Nihin yii, ní ṣiṣakiyesi Iwe Ifihan ori ogun a tun ri ẹgbẹ́ miiran - ẹgbẹ́ ti o kẹyin ninu Ajinde Kin-in-ni. Ẹgbẹ yii ni awọn ti a bẹ́ lori nitori ẹri Jesu, ati nitori Ọrọ Ọlọrun, ati awọn ti kò fori balẹ fun ẹranko naa, ati fun aworan rẹ̀, tabi ti kò si gba ami rẹ̀ si iwaju wọn tabi si ọwọ wọn. Ninu Ifihan 6:9-11 ni akọkọ sọ nipa ẹgbẹ́ yii gan an. Dajudaju awọn wọnyii padanu Ipalarada awọn eniyan mimọ́ nitori wọn kò pẹlu awọn aṣẹgun ni kikún ti wọn ti gbé gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ̀.

Wọn padanu wiwà ninu Ase-Alẹ ologo ti Igbeyawo Ọdọ-Agutan, dipo rẹ̀ a fi ipa mú wọn fara da ipọnju ẹlẹru titi de oju ikú.

**Ibiwó Ikẹyin fun Satani**

Ninu ẹsẹ kẹta ori ẹkọ́ wa, a ri pe a ko le ṣai tú Satani silẹ fun igba diẹ lẹyin itimọle rẹ̀ fun ẹgbẹrun ọdun. Awọn eniyan lori ilẹ ayé pẹlu awọn ti a bi ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun, ṣi ni ominira lati lo ọkàn wọn bi wọn ba ti fẹ a o si fun wọn ni anfaani lati yàn yala lati sin Oluwa tabi lati ni Satani ni oluwa wọn. Ọna ti Satani yoo gbà fi tan ogunlọgọ jẹ bẹẹ ni a ko sọ fun wa; ṣugbọn labẹ rẹ̀ ni wọn yoo jade wá ni iye "bi iyanrin okun," wọn o si wọ̀ inu Ilẹ Mimọ́ wọn o si yi Ilu ayanfẹ naa ká. Eyi n fi hàn pe ọkàn ti a ko ba tún bi "kún fun ẹ̀tan ju ohun gbogbo lọ, o si buru jayi." Bi ko ṣe pe a ba sọ ọkàn eniyan di funfun nipa Ẹjẹ Jesu, bi o tilẹ jẹ pe ayé yoo jẹ́ paradise tootọ fun ẹgbẹrun ọdun, eyi kò ni tó lati tẹ́ ẹlẹṣẹ lọrun.

O hàn kedere pe ète wọn ni lati já agbara ijọba gbá kuro lọwọ Oluwa ati awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀ ṣugbọn yoo yọri si igbesẹ̀ sinu ọ̀fun ikú, nitori kò si ọ̀tẹ kankan si Ọba naa ti o lè bọ́ si i rara. Ọrọ kekere kan pari itan naa: "Iná si ti ọrun sọkalẹ wá, o si jo wọn run." A mú satani a kò si sọ ọ sinu ọgbun lakoko yii ṣugbọn a sọ ọ sinu adagun iná ati sulfuru nibi ti ẹranko ati wolii eke nì wà.

Nigba ti Olugbala wa laye, O bá awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ sọrọ nipa "iná ainipẹkun, ti a ti pèse silẹ fun Eṣu ati fun awọn angẹli rẹ̀" (Matteu 25:41). Oun naa ni yii, bayii si ni ijọba Satani ni ayé pari.

**Itẹ Idajọ Nla Funfun**

Gẹrẹ lẹyin ibiṣubu ikẹyin fun Satani ati awọn ogun rẹ̀ ohun ti Apọsteli naa ri yipadà, o si wá ri Itẹ Nla Funfun kan ti Ẹni kan joko lori rẹ̀, niwaju ẹni ti ayé ati ọrun fò lọ! Johannu ri Itẹ́ miiran, eyi ti o ṣe apejuwe rẹ̀ ninu Ifihan 4, eyi ti n sọ ti igbà Ipalaradà awọn eniyan mimọ́. Itẹ́ naa ní oṣumare lori rẹ̀ lati tọka si imuṣẹ awọn ileri ti majẹmu; kò si ohun ti a le mọ eyi si bi kò ṣe titobi ati funfun eyi ti n sọ ti agbara ati idajọ pipe. Kikọrin ati fifi iyin nlá fun Ọlọrun ati Ọdọ-Agutan wà nibi Itẹ́ kin-in-ni, nitori o jẹ ibẹrẹ iṣakoso eyi ti yoo mu ère wá fun awọn eniyan mimọ́. Ṣugbọn nihin yii, kò si orin kan, tabi ohùn ayọ̀; nitori ti i ṣe idajọ eyi ti o mu awọn ti kò ri igbala lọ sinu ègbé ikẹyin. Fun apẹẹrẹ, Ẹni ti o joko lori Itẹ́ naa ni iri pataki kan -- itanṣan ti o dabi okuta jasperi ati sardi; nihin yii ni ifarahan iri Olodumare ba-ni-lẹru to bẹẹ ti ayé ati awọn ọrun tikara wọn fò lọ. Iran ti o ba-ni-lẹru yii kò fi àye silẹ rara fun ireti kankan mọ́ fun awọn ti idajọ naa wá si ori rẹ̀ ni akoko yii.

**Ajinde si Idajọ**

Ajinde kan ṣẹlẹ̀ nihin, ijadelọ agbara ayeraye sinu òkun, sinu isà-okú, sinu ipò-oku; gbogbo awọn oku alaimọ́ si duro lojiji niwaju Itẹ́ naa. Awọn ẹni nla ati kekere, awọn alakoso ati iranṣẹ, ọ̀mọwé ati òpè – gbogbo wọn wà nibẹ. A kò ri kà nipa aṣọ funfun, imọ ọpẹ, adé, tabi ohunkohun bi ko ṣe awọn ẹlẹṣẹ niwaju ọla nla Ẹni Alagbara ti wọn n duro de ègbé wọn ayeraye. Ogunlọgọ eniyan ni wọn ti wà ti wọn si ti kú lori ilẹ ayé yii, ṣugbọn igbesi-ayé ti wọn gbé, iwa ti wọn hù, èro ati ibinu ti wọn gbà layè, wà ni kikọ́ silẹ ninu awọn iwe Ọlọrun Olodumare. O ha jẹ ohun iyanu pe ogunlọgọ eniyan pupọ yii ki yoo le fọhùn rara nigba ti wọn ba duro niwaju Ọlọrun?

**Iwe Iye**

Iwe miiran fara hàn ti i ṣe Iwe Iye, iwe orukọ awọn ti a wẹ̀ ninu Ẹjẹ Iyebiye ti Jesu Kristi. O yẹ ki a ṣi eyi naa pẹlu, nitori awọn eniyan pupọ wà ti igbesi-ayé wọn dara ti wọn si jẹ́ oloootọ, awọn ti wọn wà ti wọn si kú pẹlu ero pe awọn ti mú gbogbo iwa rere hù, ṣugbọn ti wọn kò ka a si ohun gúnmọ lati ni etutu nipa ilaja Olugbala ti a kàn mọgi. Ọpọ̀ ni ẹbi wọn ti o pọju jẹ́ ti ẹ̀ṣẹ ainaani: ki i ṣe pe wọn jẹ́ ẹlẹṣẹ ti o buru jù tabi pe wọn ṣe ohun irira kan, ṣugbọn wọn ti ṣai naani iru igbala nla bi eyi. Bi orukọ ẹnikẹni kò ba si ninu iwe ọ̀wọ nì, bi o ti wu ki o gbé igbesi-ayé rere ati titọ́ tó, kò si iranwọ fun un.

A sọ ọrọ-idajọ; a sọ ìya rẹ̀ a si mu un ṣẹ lẹsẹkẹsẹ. Ẹnikẹni ti a kò ba ri orukọ rẹ̀ ninu Iwe Iye, a sọ ọ sinu adagun iná. Eyi ni a n pè ni “ikú keji.” Lati inu ọ̀rọ yii, “ikú,” awọn miiran le rò pe itumọ eyi ni ipari wiwà, tabi iparẹ́. Ṣugbọn ẹranko ati wolii èke naa wà ninu ikú yii fun ju ẹgbẹrun ọdun lọ; wọn ṣi wà laaye gan an ni opin akoko naa. Ninu ẹsẹ 10 a kà pe, “Nibiti ẹranko ati woli eke nì gbé **wà**, a o si mã dá wọn loro t’ọsan-t’oru lai ati lailai.” Marku 9:47 ati 48 n tọka si awọn eniyan buburu ti a gbé “sọ sinu iná ọrun apadi: nibiti kòkoro wọn ki ikú, ti iná na ki si ikú.”

**Opin**

Njẹ pẹlu awọn ọ̀rọ ẹ̀ru otitọ wọnyii ki ni a le sọ nipa awọn ti wọn mọọmọ ti wọn si ṣe ipinnu lati maa rin lọ ninu ọna ti kò ni iyọrisi bi ko ṣe ikú keji yii? Jesu wi pe, “Ẹnyin o ti ṣe yọ ninu ẹbi ọrun apadi?” (Matteu 23:33). Awọn wọnni n kọ́ ti wọn ti ta ẹmi wọn fun ọrọ̀, fun afẹ́, fun ohun ini ayé yii? Wolii nì ti sọrọ pe: “Ipò-okú ti fun ara rẹ̀ li àye, o si là ẹnu rẹ̀ li aini iwọn: ati ogo wọn, ati ọ̀pọlọpọ wọn, ati ọṣọ́ wọn, ati awọn ẹniti nyọ̀, yio sọkalẹ sinu rẹ̀” (Isaiah 5:14).

Pagà, irora ti ko ṣe e fi ẹnu sọ ti olukuluku ọkàn ègbe yoo ni bi o ti n kuro niwaju Itẹ Idajọ Nla Funfun nì ti a si gbé e sọ sinu adagun iná lae ati laelae! Irora yoo di pupọ si i nigba ti ẹni kọọkan wọn ba wa mọ pe aba ati là ti wà fun wọn ninu Jesu Kristi ati Etutu Rẹ̀; ṣugbọn ẹni kọọkan yoo boju wo ẹyin si igba tabi iye igba ti o ti kọ aanu ti a fi lọ̀ ọ, ṣugbọn nisisiyii aanu ti rekọja lae. Iwọ ti n ka iwe yii ṣugbọn ti a kò i ti gba ọkàn rẹ là, Ọrọ Ọlọrun tun n kede pe: “Kiyesi i, nisisiyi ni akokò itẹwọgba: kiyesi i, nisisiyi ni ọjọ igbala.”

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni yoo ṣẹlẹ si Satani ni ikẹyin ọjọ?
2 Ṣe apejuwe ọ̀tọtọ ipa ti Ajinde Kin-in-ni pin si.
3 Lori awọn wo ni ikú keji kò lagbara?
4 Ṣe alaye bi yoo ṣe le ṣe e ṣe fun S atani lati le ni ọmọlẹyin ti o pọ̀ to eyi nigba ti a ba tú u silẹ kuro ninu ọ̀gbun.
5 Ṣe apejuwe iran ibi Itẹ Idajọ Nla Funfun.
6 Ipa wo ni Iwe Iye ni ṣe ninu idajọ yii?
7 Ki ni abayọrisi idajọ yii?